Ọlọ́run Wo Hesekáyà Sàn

Ìtọ́ni: Ibi tí kò sí ariwo ni kó o ti ṣe ẹ̀kọ́ yìí. Tó o bá ṣe ń ka àwọn ẹsẹ Ìwé Mímọ́ tó wà níbẹ̀, máa fojú inú wò ó bíi pé o wà níbi tọ́rọ̀ náà ti ṣẹlẹ̀, kó o sì máa fọkàn yàwòrán ohun tó ń ṣẹlẹ̀. Jẹ́ kó dà bíi pé ò ń gbọ́ bí àwọn èèyàn náà ṣe ń sọ̀rọ̀. Ronú nípa bí ohun tó ò ń kà yẹn ṣe máa rí lára àwọn èèyàn wọ̀nyẹn. Kó o sì máa fojú inú wò ó bí ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́.
Àwọn tó wà nínú ìtàn yìí: Hesekáyà, Aísáyà
Ohun tó ṣẹlẹ̀: Hesekáyà ń ṣàìsàn, ó gbàdúrà sí Ọlọ́run, ara rẹ̀ sì yá.

1 RONÚ NÍPA OHUN TÓ ṢẸLẸ̀.—KA AÍSÁYÀ 38:1-9.

Fojú inú wo bí àdúrà Hesekáyà ṣe máa jinlẹ̀ tó, kó o sì ṣàlàyé rẹ̀. (*Túnṣẹ 3 kà.*)

Báwo lo ṣe rò pé Aísáyà máa sọ̀rọ̀ nígbà tó ń jíṣẹ́ tí Jèhófà rán an, bó ṣe wà nínú Aísáyà 38:5-8?

Kí lo rò pé Hesekáyà máa ṣe nígbà tí Aísáyà sọ fún un pé ara rẹ̀ á yá, pé kò sì ní kú?

2 ṢÈWÁDÌÍ KÓ O SÌ RONÚ JINLẸ̀.

Yàtọ̀ sí àìsàn tó ń ṣe Hesekáyà, kí ló tún ṣeé ṣe kó máa rò? (Amọ̀nà: Ka Aísáyà 36:1; 38:6.)

Kí ló ṣeé ṣe kó mú kí Jèhófà gbọ́ àdúrà Hesekáyà? (Ka 2 Kíróníkà 31:20, 21; Aísáyà 38:3.)

Kí ló ṣeé ṣe kó mú kó ṣòro fún Aísáyà láti pa dà lọ jíṣẹ́ tó yàtọ̀ sí ohun tó kọ́kọ́ sọ fún Hesekáyà?

Báwo lo ṣe mọ̀ pé iṣẹ́ ìyanu gidi ló ṣẹlẹ̀ nígbà tí òjìji pa dà séyìn, pé kì í ṣe àlá lásán? (Ka 2 Kíróníkà 32:24, 31.)

www.jw.org © 2013 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 WO BÍ O ṢE LÈ FI OHUN TÓ O KỌ́ SÍLÒ.

Ṣe àkọsílẹ̀ ohun tó o kọ́ nípa . . .

Bó ṣe máa ń wu Jèhófà láti gbọ́ àdúrà wa.

Bí a ṣe lè ní orúkọ rere lọ́dọ̀ Ọlọ́run.

4 BI ARA RẸ PÉ:

Àwọn nǹkan wo ló lè ṣẹlẹ̀ sí mi tó yẹ kó mú kí n túbọ̀ gbàdúrà sí Jèhófà?

Báwo ni mo ṣe lè mú kí àdúrà tí mò ń gbà túbọ̀ dára sí i kó sì nítumọ̀?

Kí ni mo kọ́ nínú ìtàn yìí tó ṣe pàtàkì sí mi jù, kí sì nìdí?

Àbá: Ṣọ ìtàn yìí bí ìgbà tí ò ń ṣọ ìròyìn. Ròyìn ohun tó ṣẹlẹ̀, kó o sì ṣe bíi pé ò ń fọ̀rọ̀ wá ọ̀rọ̀ wò lẹ́nu àwọn tó wà nínú ìtàn náà àti àwọn tí ọ̀rọ̀ ṣojú wọn.

JW .ORG™

Wa èdà PDF yìí jáde lórí www.jw.org/yo

www.jw.org © 2013 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania